LAKAYE ORO

Ko ologbon, yio si ma a gbon siwaju, ko olododo on yio si ma a po si i ni imo, Iberu Oluwa ni ipilese ogbon.

# Irohin Yoruba

NO. 930 WEDNESDAY APRIL 10 —TUESDAY APRIL 16, 1963 KOBO MEJI 2D

**Kere o!**

Fun irohin ti o pe yekeyeke, ti o si dun ju oyin lo, mase alai ra Irohin Yoruba losose. Ra Irohin Yoruba ni ose ti mbo fun orisirisi "iwe si Olotu" lori ohun ti o nsele ni [illegible] run loni

## LEHIN ISORO ATI INUNIBINI TI O KOJA AFENUSO

# JESU SEGUN IKU



ONIGBAGBO EHO IHO AYO !

## ISA, OKU ISEGUN RE DA?

Aki gbogbo awon onkawe Irohin Yoruba ku odun Ajinde. Ki Olorun sodun labo fun gbogbo wa. Gegebi Jesu ti jiya ti o si farada isoro beni o to fun gbogbo awa ti o fe ri ilosiwaju ati igbega orile ede Yoruba lati fohun sokan fun atilehin ati iforiti egbe Afenifere ni asiko yi, nitorina igbagbo wa nipe Egbe Afenifere yio segun isorokisoro ati otakota.

## ROSIJI TUN JA TILE, O RO GBI

Ireti Egbe UPP ja sofo nigbati awon kuna lati bo si ipo asiwaju egbe Alatako ni ile igbimo Asofin apapo Naijiria ni ojo ru ti ise ojo ketadinlogbon osu keta odun yi nitoripe awon omo egbe Afenifere tayo awon omo egbe UPP fiofio. Ajanaku ki ise eru omode.

Kete ti Gomina-Agba soro tan ni egbe UMBC so gbangba pe gbogbo awon omo egbe won ti o wa ni Ile Igbimo Asofin Apapo Naijiria faramo egbe Afenifere timotimo.

**IPINNU OJIJI**

Ipinnu y[illegible] mu ki awon omo egbe Afe[illegible]ifere di mokandinlogbon , [illegible]be Omolangidi si di mokanlelogbon,.

Ko faramo egbe kankan si e meta alatako ninu oro ti Ogbeni Jonah Asadugu so, o ni egbe UMBC ko faramo oro ti Olotu Ijoba Apapo Naijiria, Olola Abubakar Tafawa Balewa so bayi pe "ofin ko i ti toka si enikeni nisisiyi gegebi asiwaju UPP alatako ni ile Igbimo Asofin Apapo Naijiria.

Siwaju sii, Egbe UMBC so bayi pe "kii se eto olotu Ijoba Apapo Naijiria lati lowo ninu oro yiyan olori alatako gegebi kii ti ise eto egbe alatako Ijoba Apapo Naijiria lati lowo si yiyan Olotu Ijoba Apapo Naijiria"

Awon omo egbe alatako ni o ni eto lati yan olori alatako Ti Olola Abubakar ba nwa ipo olori alatako iba dara ti o ba le fi ipo re sile, a o si gba a sinu omo egbe alatako ni gege bi imore ba ti mo." Egbe UMBC lodi si oro ti olola Abubakar so pe "ijoba ti o ba wa ni ori aga ni o le fowo saiya pe enikan ni olorin alatako".

Siwaju sii, egbe UMBC ni, "aibiti ijoba ododo ba fi ese mule, ipo olotu ijoba apapo ati olori alatako wa ni ikawo awon adibo. Asiwaju egbe ti o ba po ju lo ni Ile Igbimo Asofin Ijoba Apapo nii se olotu Ijoba Apapo olori egbe ti o ba kere julo ni olori alatako.

# Irohin Kakiri Aiye

## Ran awon eree lowo Da ehin didun dun

*Ra Mendaco*

## ETE IGBIMO OGBON EWE

## Coker T'ajo de

## OTEGBEYE JARE




## AWON OGBOLOGBO IRORA ORIKE-ARA TI LO!



KRUSCHEN SALTS




# AWORAN IROHIN



IBEWO ORA 'BIRIN SI BRIBANE

"MOLE KE "MI NOMBA"



Aworan yi ni ibiti Tiger yio ti ba Gene Fulmer ja

## National Bank of Nigeria Ltd. Ileya Shilling Fund - May, 1963

Depositors in the Ileya Shilling Fund are hereby reminded that, in accordance with the Regulations governing the Fund, they may withdraw their deposits as from Monday, 15th April, 1963.

Withdrawals can only be made by the depositor in person and on production of his Passbook. In the case of distant depositors, early application for a withdrawal form should be made to the Manager of the Branch concerned, each application to be accompanied by the depositor's Passbook for ... up.

Withdrawals for the year will close on the 11th May, 1963, and depositors who fail to withdraw on that day cannot do so until next Ileya.

Payment shall be made in the following alphabetical order of the depositors' surnames on the date shown hereunder and contributors who fail to apply on the prescribed date shall not be attended to until Monday, 22nd April, 1963.

| | | |
|---|---|---|
| A | — Monday, | 15th April |
| B — H | — Tuesday, | 16th „ |
| I — N | — Wednesday | 17th „ |
| O | — Thursday | 18th „ |
| P — Z | — Friday | 19th „ |
| A & O | — Saturday, | 20th „ |

For the year 1964, deposits will be taken as from Monday, 13th May, 1963.

BY ORDER OF THE MANAGER.




# OJO TI AWO ATI ZIK PADE

**Ni ojo keta osu keris odun yi Oloye Obafemi Awolowo, Babasale egbe Afenifere Naijiria so fun ile ejo giga kan ni Eko nibiti o ti njejo pelu ogun enia miran lori esun idite si Ijoba pe on ati Gomina-Agba Naijiria Dokita Nnamdi Azikiwe pade ni Londonu ni agogo marun irole ojo karundinlogun osu kejo odun 1961 lati jiroro lori isokan egbe Alakuko ati egbe Afenifere.**

Oloye Awolowo so wipe on lo si ile Dokita Azikiwe ni ogun'jo osu kesan odun 1961 ni kete ti Ile Eko Nla Unifasiti Nsukka fi oye ijinle ofin daa lola.

O ni on fi ye Dokita Azikiwe gbangba pe on setan lati baa se ise po ati pe nigbati o ba to akoko lati yan Aare ile Naijiria, gbogbo awon adibo fun egbe Afenifere ni yio dibo fun Dokita Azikiwe nitoripe on Oloye Awolowo ko ni gbe ara on sita fun idibo si ipo Aare Naijiria.

Oloye Awolowo fi ye adajo, agba Ogbeni Sowemimo wipe ogunlogo awon omo egbe Alakuko ni on ti ba soro nipa wipe o ye ki egbe Afenifere ati Alakuko gbagbe ija won, ki nwon si parapo lati gba akoso Ijoba Apapo ni ona eto lowo egbe Olomi ti o nfi ipa se iselu.

Ninu awon omo egbe Alakuko ti o pade Oloye Awolowo lori eto idapo egbe mejeji na ni : Oloye Adewale Fashanu Babasale egbe Zikist National Vanguard; Ogbeni Chike Ekwuyasi, Olori Agba egbe Alakuko ati Oloye Kola Balogun ti ise Adele Alaga Igbimo eto Ise egbe Alakuko ni Ipinle Iwo Orun ni odun 1961.

Oloye Awolowo so ni ile ejo wipe nigbati Oloye Festus Okotie-Eboh mo ibatan ti o wa larin on ati awon asiwaju egbe Zikist National Vanguard, o gba awon moto won lowo won nitori ki nwon ma baa le jade, Oloye Awolowo wa so gbangba wipe egbe Afenifere ni o gbe awon moto ropo fun awon asiwaju egbe Zikist National Vaguard na.

Oloye Awolowo so pe lati le pari ija iselu ti o wa larin on ati Dokita Azikiwe, ohun meta ni on se: "Mo koiwe daradara kan si nigbati odi Gomina-Agba Naijiria. Gbogbo awon eto aseye nipa oye Gomina-Agba ti o je ni mo lo si ati pe nko jeki egbe Alatako tako owo ti ijoba bu fun ipo Gomina-Agba ninu ile Igbimo Asofin Apapo .

Oloye Obafemi Awolowo wa fi awon iwe ti Oloye Kola Balogun, Oloye Adewale Fashanu ati Ogbeni Ayo Fasanmi ko sii lori eto idapo egbe Afenifere ati Alakuko han ile ejo. Adajo si gba awon iwe na gege bi ohun eri.



## OBA KANO FI OYE SILE

Irohin na fi ye ni pe oba Mahammadu fi ipo re sile lale ojo kejidinlogbon osu keta odun yi lehin ti Gomina ipinle Ariwa, Olola Kashim Ibrahim ti gba imoran awon ijoye re, ninu ipade igbimo ti nwon se.

Siwaju sii, nwon ni eto ni ki Olola Mahammadu fi ipo re sile ; ki aye ba le wa fun ijoba ipinle na lati se eto atunse ni Kano".

Lasiko ti iwadi Igbimo Muffetmba ise re lo ni nwon palase pe ki nwon wa akobi oba na lo. Ni ojo Ketala osu kejila odun ti o koja yi, nwon pe oba na fonrara re lati wa duro soro ninu apoti eleri niwaju igbimo iwadi na.

## BABATOLA KILO FUN FANI.

**Oloye J. E. Babatola Omo Egbe Afenifere ti ise Asoju Ekiti ni Ile Igbimo Asofin Ipinle Iwo Orun Naijiria kilo fun Ogben R. A. Fani-Kayode, igbakeji Olotu Ijoba Ipinle Iwo Orun Naijiria pe ki o dekun lati maa ko awon digbolugi enia lehin lo si irin-ajo re lati iu de ilu.**

Oloye Babatola ni, "asakasa yi ko ba dawo duro, alafia ati Ijoba ifokanbale yio pare ni Ipinle na."

Ni ojo 'ru ti ise ojo ketadinlogbon osu keta odun yi ni Ogbeni Fanikayode bere Irin-Ajo re ni agbegbe Ekiti. Ninu ikede kan ti Oloye Babatola se ni Ibadan ni ojo 'Ru ti ise ojo ketadinlogbon Osu keta odun yi, o kilo fun Fani-Kayode pe ti o ba fe gba iyi lodo awon Omo Ekiti kio ma ko awon digbolugi enia lehin de odo won.

O si tun kesi igbakeji Olotu Ipinle Iwo Orun na pe ki o lo ipo re lati ki owo Ogbeni R. A. Akinyemi Minista Alakoso eto oye bo aso nipa bi o ti se nse ise iselu tire.




"IG[illegible]AWO NA"

[illegible] awon awoṛan [illegible] "IGBEYAWO NA" [illegible] Sugbọn [illegible]



Ọdọmọkunrin [illegible] orukọ rẹ njẹ Kwesi [illegible] lati kọ iwe ati lati ma f'owo pamọ bi agbara rẹ ti mọ. Nigbati o si pada, ohun to kọkọ ṣe nipe, o bẹrẹ f'owo pamọ sinu banki ti Barclays. Larin akoko yi, nwn lo ku ki okunrin bubura kan ji olufẹ rẹ gbe lọ.



**Iwọ ha lè gbe iyawo bi? Iwọ le ṣe bẹ laipe lọ titi bi o ba bẹ̀re lati ma f'owo pamọ ni ọdọ Barclays nisiyi!**

Latigba dogba ni ki o ma f'owo pamọ, ki o si tọju rẹ s'ile ipamọ owo. Fi ọkan tan Barclays nipa itọju owo rẹ, eyiti iwọ yio si gbà pada yio si ju iye ti o fisibẹ lọ! *Lọ bẹ̀re* ni banki ti Barclays tombẹ nitosi ọdọ rẹ nipa fifi owo rẹ pamọ. Awọn ni yio fun ọ ni imọran ati iranlọwọ to darajulọ.

Sugbọn gbogbo rẹ yọri si ayọ nikẹhin nigbati Kwesi mu gbogbo [illegible] na - pẹlu ẹkunrin bubura yen - lọ wo iye owo rẹ tombẹ ni Barclays Bank.

Iwọ na gbọdọ bẹrẹ lati ma f'owo pamọ, nitoripe igbeiyawo ama na enia l'owo lọpọlọpọ!

BARCLAYS BANK DCO


Published by the Eastern Post Limited Elephant House, 214 Broad Street, Lagos and printed for them by the Olughadewa Press 21 Ajele Street, Lagos Acting Editor (Adele Olotu) E. O. OLOFIN. N2/439 Shittu Steet, Ibadan.